Njinga & Sepé: Revista Internacional de Culturas, Línguas Africanas e Brasileiras
São Francisco do Conde (BA) | vol. 5, nº Especial I | p. 172-187 | jan./ jun.2025.

# Ìpera-ẹni-níjà nínú Ìṣeré Orin Agbè

# Self-Defense in the Music of the Tribe

**Luqman Abísọ́lá KÍARÍBẸ̀Ẹ́** *
ORCID iD https://orcid.org/0000-00019894-8251

**ÀṢAMỌ̀**
Ọ̀kan nínú orin kóríyá láàárín àwọn Yorùbá Ọ̀yọ́ ni orin agbè jẹ́. Orin agbè jẹ́ orin ogun, a sì máa ń kọ ọ́ ní ààfin àwọn Ọba Ọ̀yọ́, àgbàlá àwọn jagunjagun àti ibi ayẹyẹ lóríṣiríṣi. Torí pé orin agbè jẹ mọ́ agbaja ṣíṣe púpọ̀, àwọn òṣèré rẹ̀ máa ń pe ara wọn níjà kí adùn eré náà le hànde. Ìwádìí yìí yàn láti ṣe àgbéyẹ̀wò ọ̀nà tí àwọn ọ̀kọrin agbè máa ń gbà pe ara wọn níjà lásìkò eré. Tíọ́rì ìlò-àmì nínú ewì ti Riffaterre (1978) ni a ṣe àmúlò fún àtúpalẹ̀ détà. Àwọn ìṣeré orin agbè tí a gbà sílẹ̀ ni détà àtúpalẹ̀ iṣẹ́ ìwádìí. A ṣe àmúlò àwọn ọ̀nà-ẹnu Yorùbá mìíràn láti ṣe àlàyé détà iṣẹ́-ìwádìí yìí jìnlẹ̀. Àbájáde ìwádìí fi hàn pé àwọn òṣèré orin agbè máa ń pe ara wọn níjà nínú agbè lílù, orin kíkọ, ìṣeré ojúlówó, ijó jíjó/òkìtì títa/idán pípa fún ìdárayá, níní ìgboyà àti àmúlò òògùn ìkà fún ogun jíjà. Ìwádìí tún fi hàn pé ìpèra-ẹni-níjà àti kóríyá gan-an ni kókó pàtàkì tó ṣe okùnfà ìgbéǹde ìṣeré orin agbè. Ìdí sì nìyí tó fi jẹ́ pé láàárín àwọn jagunjagun Ọ̀yọ́ Ilé ni orin náà ti bẹ̀rẹ̀. Iṣẹ́ yìí tún fi hàn pé ìṣeré orin agbè jẹ́ ọ̀nà-ìdẹ́rùbọ́tá lójú ogun. Ìwádìí jẹ́ ká mọ̀ pé lára ìdí tí orin agbè kò ṣe tí ì parẹ́ di àsìkò yìí ni pé ó jẹ́ orin agbaja fún àwọn ènìyàn Ilé Gbọ̀ńkáà ní Igbó-Ọrà, Ìbàràpá àti pé ó jẹ́ orin ọba Onímia, Ìmià Òkè-Ògùn, Ìpínlẹ̀ Ọ̀yọ́.

**KÓKÓ-Ọ̀RỌ̀:**
Ìpera-Ẹni-Níjà, Kóríyá, Ìṣeré Orin Agbè, Orin Ogun, Tíọ́rì Ìlò-Àmì Nínú Ewì

**ABSTRACT**
Orin agbè is one of the songs of stimulation among the Yorùbá people of Ọ̀yọ́. It is a war song, also sung at the palace of the kings of Ọ̀yọ́, compounds of warlords and social ceremonies. Because orin agbè is full of stimulation, its performers challenge one another to realise the full aesthetics of the song. This study appraises how the performers of orin agbè challenge one another during its performance. Riffaterre's (1978) semiotics of poetry is employed for data analysis. The study's primary data are the recorded videos of the performances of orin agbè. Some other Yorùbá oral genres are employed for critical analysis of research data. The study reveals that the performers of orin agbè challenge one another in agbè instrumentation, song rendition, quality performance, dance styles/acrobatic and magical displays for entertainment, courageous stimulation and use of baleful charms at battle-field. The study also reveals that challenging and stimulating one another are the main reasons behind the performance of orin agbè. That is the reason the song was originated among the Old Ọ̀yọ́ warlords. It is also revealed in the study that orin agbè is a way of scaring enemies at battle-field. The study explicates that among the factors that have contributed to the sustenance of orin agbè is its use as a song of amusement among the people of Gbọ̀ńkáà's household at Igbó-Ọrà, Ìbàràpá and also the song of the King Onímià, Ìmià town in Òkè-Ògùn, Ọ̀yọ́ State, Nigeria.

---

* College of Humanities and Culture, Osun State University, Osogbo, Nigeria, E-mail: luqman.kiaribee@uniosun.edu.ng & luqman.abisola@gmail.com

**KEYWORDS**
Self-challenge, Amusement, Orin Agbè Performance, War Song, Semiotic Of Poetry

**Ìfáárà**

Orin jẹ́ ọ̀kan pàtàkì nínú ẹ̀yà ewì Yorùbá (Kíaríbẹ̀ẹ́, 2023; Ògúndèjì, 1991; Ọlátúnjí, 1984; Olúkọ̀jú, 1985). Ohùn tó rin kinkin, tí ìwéhùn àti ìwọ́hùn rẹ̀ gún régé, ẹ̀yí tí a le kọ ní ìlànà lílé àti gbígbè, tàbí ní ìlànà àdákọ, ẹ̀yí tí a le lu ilù, ṣápẹ́ tàbí pa atẹ́ sí, tí ó sì ṣe é ṣe kí á jó sí ni orin jẹ́. Orin ni ẹ̀yà ewì tí ìwọ́hùnrọ̀rọ̀ rẹ̀ gunpá jùlọ. Ẹ̀yí ló sì fà á tí ó fi ṣe é gbè ju ìsàré àti àrángbọ́ lọ. Bí ìsàré bá dùn dé ògóńgó ni ó máa ń di orin. Kò sí ẹ̀yà kan ní àgbáyé tí kì í kọrin. Ọ̀nà àgbákalẹ̀ àti irúfẹ́ orin tí kálukú ń kọ ni ó máa ń yàtọ̀. Yorùbá ní oríṣiríṣi ìgbàgbọ́ nínú orin. Yorùbá gbà pé ọ̀rọ̀ ló dorin. Torí náà, bí wọ́n bá fẹ́ báni sọ̀rọ̀, wọ́n le kọ ọ́ lórín. Bí a bá wo ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọ̀kọrin Yorùbá, ṣààṣà ni ẹ̀yí tí kì í kìlọ̀ ìwà ọmọlúàbí nínú orin wọn.

Ọ̀rọ́ tí àwọn ọ̀kọrin wọ̀nyí ní lọ́kàn láti bá àwọn olùgbọ́ wọn sọ ni wọ́n sọ di orin. Yorùbá a tún máa sọ pé “Ọwọ́ ní í ṣíwájú ijó, orin ní í ṣíwájú ọ̀tẹ̀.” Ohun tí Yorùbá gbà lérò níbí ni pé, ènìyàn le fi orin pilẹ̀ ọ̀tẹ̀ àti ìjà. Irúfẹ́ àwọn orin báyìí ni orin olórogún, orin olóṣèlú, orin ogun gẹ́gẹ́ bí orin agbè, àti orin ẹkún ìyàwó. Orin jẹ́ àmì ìfẹ́ àti gbígbà-fún-ara-ẹni. Ìdí nìyí tí Yorùbá fi máa ń sọ pé “A ò fẹ́ ọ nílùú, ò ń dárin, bí o bá dárin náà tán, tani yóó bá ọ gbè é.” Ẹ̀yí fi hàn pé ọ̀tá ẹni kò le dárin fúnni ká gbè. Ẹ̀yí ló tún máa ń mú Yorùbá sọ pé “A kọ ọ́ kán, a gbè é kùù, orin àmọ̀tẹ́lẹ̀ ni.” Ẹ̀yí ń tọ́ka sí i pé, a kì í gbe orin tí a kò mọ̀ tẹ́lẹ̀ kó dán mọ́nrán àti pé ẹni tí a kò fẹ́ tẹ́lẹ̀ kò le dá orin kí ènìyàn gbè é.

Bí a bá tún wo ohun tí a sọ nípa orin gẹ́gẹ́ bí àmì ìjọ́hẹn tàbí ìgbàwọ̀fún, òwe Yorùbá kan jẹ́ ká mọ̀ pé “Orin tí Ẹ̀lúkú bá dá, ni ọmọ rẹ̀ máa ń gbè.” Òwe yìí tọ́ka sí i pé nínú orò àti ìsìn òrìṣà tí a mọ̀ sí Ẹ̀lúkú, Ẹ̀lúkú àti àwọn ọmọ ìṣòrò rẹ̀ kì í ja ara wọn níyàn. Ohun tí ó bá sọ gẹ́lẹ́ ni àwọn ọmọ náà gbọ́dọ̀ sọ. Òwe yìí tún fi hàn bí Yorùbá ṣe máa ń lo orin nínú àwọn ìlànà ìjọ́sìn wọn. Àwọn Yorùbá a tílẹ̀ tún máa sọ pé, “Orin tí kò ṣòro ó dá, kì í ṣòro ó gbè.” Ẹ̀yí jẹ́ kí á mọ̀ pé bí orin bá ṣe rọrùn tó láti dá náà ni yóó ṣe rọrùn tó láti gbè. Ẹ̀yí tún tọ́ka sí òwé Yorùbá mìíràn tó sọ pé “Ohun tí kò le, kò wá ọ̀bẹ.” Bí Yorùbá ṣe ń fi orin ṣe àpọ́nlé ẹni náà ni wọ́n máa ń fi orin ta àbùkù ènìyàn. Nínú orin ọ̀tẹ̀ àti orin olórogún tí a mẹ́nubà lókè yẹn, àyè wà fún ẹni tí a fi orin bú láti dá èsì padà nígbà tí olúwà rẹ̀ bá mèsì ọ̀rọ̀, tí kì í sì í ṣe ọmọ lọ-ilé-lọ-mésì-wá. Ẹ̀yí ló fà á tí Yorùbá fi máa ń sọ pé “Ẹni ọ̀rọ̀ kò dùn ní í kọrin èébú, ìbi a bá ti búni n là á wòye.” Ohun tí ẹ̀yí tún tọ́ka sí nípa orin ni pé, bí ẹnìkan bá forin búni, àyè wà láti bú olùwà rẹ̀ padà. Bí ẹni tí ọ̀rọ̀ bá máa ń dùn bá bú ẹlòmíràn, tí ẹni tí a bú náà sì bú tirẹ̀ padà, ó le fa ìjà, ó sì le di aáwọ̀. Ìdí nìyí tí Yorùbá fi kì í nílọ̀ pé ẹni tí ọ̀rọ̀ bá máa ń dùn kò yẹ láti kọrin èébú bú ẹlòmíràn.

Torí oríṣiríṣi nǹkan tí Yorùbá ń lo orin fún wọ̀nyí ni Yorùbá ṣe ya oríṣiríṣi orin sọ́tọ̀. Lára àwọn oríṣi orin ni orin èébú, orin ìjọ́sìn, orin ọdún ìbílẹ̀, orin ìbejì, orin ìrẹmọlẹ́kún, orin àmúṣẹ́yá, orin òṣèlú, orin eré ìdárayá àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ (Kíaríbẹ̀ẹ́, 2023; Ògúndèjì, 1991; Olúkọ̀jú, 1978 & 1985; Ọ̀pádọ̀tun, Gbénró & Ọmọ́làsóyè, 2005; Raji, Adéọlá, Òjó, Táíwò & Àjùwọ̀n, 2009). Ọ̀kan pàtàkì lára orin tí Yorùbá máa ń kọ ní ojú ogun ni orin àgbè (Àlàbá, 1985; Kíaríbẹ̀ẹ́, 2023; Ọ̀pádọ̀tun, 2002). Orin agbè yìí náà ni a tún ń pè ní orin ṣàkàrá (Àlàbá, 1985; Kíaríbẹ̀ẹ́, 2023; Ògúndèjì, 1979). Ògúndèjì (1979) ṣe àlàyé pé láti Ìlọrin ni àwọn babańlá àwọn ènìyàn ilú Ìmià ti kọ́ nípa ìṣeré orin agbè, tí wọ́n sì sọ orin náà di eré ìbílẹ̀ wọn. Àlàbá (1985) ló ṣe àlàyé jinlẹ̀ pé láti ìlú Ọ̀yọ́ Ilé ni àwọn ènìyàn ìlú Ìlọrin tí kọ́ àṣà orin agbè kíkọ.

Àlàbá (1985) àti Ọ̀pádọ̀tun (2002) ṣe àlàyé láti tẹ̀ síwájú pé ní ayé Ọba Ṣàngó, tí a tún mọ̀ sí Aláàfin Babáyẹmí Ìtíolú, ni orin yìí bẹ̀rẹ̀. Àlàbá tún jẹ́ kí á mọ̀ pé Ọba Ṣàngó, tàbí Gbọ̀nńkáà tó jẹ́ ọ̀kan nínú àwọn ìjòyè ogun rẹ̀ ni ó bẹ̀rẹ̀ orin náà. Ọ̀pádọ̀tun (2002) tilẹ̀ là á mọ́lẹ̀ pé Ṣàngó gan-an ni ó bẹ̀rẹ̀ orin agbè. A sì máa ń fi orin yìí pè é láti ṣe kóríyá fún un àti àwọn ọmọ ogun rẹ̀ lásìkò tí ó bá ń lọ sí ojú ogun. Ọ̀pádọ̀tun fi kún àlàyé rẹ̀ pé bí Ìtíolú

bá ti gbọ́ orin agbè, agbára rẹ̀ yóò di ọ̀tun, èyí yóò sì mú un jagun bí ó ṣe yẹ. Àlàbá jẹ́ kó yé wa pé kì í ṣe pé Ọba Ṣàngó nìkan ni ó lo orin yìí láti fi jagun, nínú àwọn jagunjagun tí ó tẹra mọ́ àmúlò ṣàkàrá lójú ogun ni Gbọ̀nńkáà àti Àfọ̀njá ti ìlú Ìlọrin. Àfọ̀njá yìí náà ni ìwádìí Kiáríbẹ̀ẹ́ (2023) fi hàn pé ó dá orin agbè sílẹ̀ ní ìlú Ìlọrin.

Láti gbe ẹ̀rí Àlàbá (1985) lẹ́sẹ̀ nípa pé Gbọ̀nńkáà náà lo orin agbè lójú ogun, Kíaríbẹ́ẹ̀ (2023) fi hàn pé àwọn ènìyàn Ilé Gbọ̀nńkáà, tí a tún mọ̀ sí Ilé Ajóṣàkàrá, ní ìlù Igbó-Ọrà gbà pé babańlá àwọn, tí a mọ̀ sí Gbọ̀nńkáà ló dá orin agbè sílẹ̀ ní Ọ̀yọ̀ Ọ̀rọ̀, èyí tí a tún mọ̀ sí Ọ̀yọ́ Ilé. Kíaríbẹ̀ẹ́ (2023) fi hàn pé Gbọ̀nńkáà lo orin náà gẹ́gẹ́ bí ohun ìdẹ́rùbọ̀tá àti pé àwọn àrọ́mọdọ́mọ rẹ̀ máa ń kọ orin náà gẹ́gẹ́ bí orin agbaja lásìkò tí wọ́n bá ti ní ayẹyẹ kan láti ṣe. Kò sí ẹni tó ta kò ó pé àwọn ọ̀kọrin agbè/ajóṣàkàrá máa ń fi orin yìí ṣe kóríyá, wọ́n fi máa ń ṣe ayẹyẹ, wọ́n sì tún máa ń fi ṣe agbaja lásìkò tí kò sí ogun nínú àwọn onímọ̀ tó ti ṣe iṣẹ́ lórí orin agbè. Torí náà, bí a ṣe le rí orin agbè ní ààfin àwọn ọba ilẹ̀ Yorùbá Ọ̀yọ́ náà ni a le rí i lágbàlá/ilé àwọn jagunjagun àti àwọn àgbà ìjòyè ilẹ̀ Ọ̀yọ́.

Ó yẹ kí á yán an pé àwọn orin kan wà ní ilẹ̀ Ọ̀yọ́ bákan náà tó fi orúkọ jọ orin agbè. Àpẹẹrẹ irúfẹ́ orin wọ̀nyí ni igbá títí, orin kèǹgbè àti orin kete. Àwọn ayaba Ọ̀yọ́ ló máa ń tí igbá láti fi jí Aláàfin. Ẹ̀yà orin yìí wà ní Ìlọrin náà gẹ́gẹ́ bí orin kèǹgbè. Àwọn ayaba ni ó máa ń kọ orin kèǹgbè, wọn a sì máa lò ó láti fi sin ọmọ relé ọkọ ní ààrín àwọn ẹ̀yà Fúlàní Ìlọrin. Gẹ́gẹ́ bí Owólabí (1974), Àlàbá (1985), Ọ̀pádọ̀tun (2002) àti Kíaríbẹ̀ẹ́ (2023) ṣe fi hàn, irúfẹ́ orin kan ni orin kete jẹ́ láwùjọ àwọn Ọ̀yọ́. Gẹ́gẹ́ bí orin ayẹyẹ ni Owólabí (1974), Àlàbá (1985) àti Ọ̀pádọ̀tun (2002) ṣe fi orin yìí hàn. Kíaríbẹ̀ẹ́ (2023) ló jẹ́ ká mọ̀ pé orin òrìṣà Alárá-Igbó, Ọbàtálá, Ẹgbẹ́, Ìbejì, Kórìkóto, Ìrókò àti àwọn òrìṣà tí ó jẹ mọ́ obìnrin àti ọmọdé ní orin kete jẹ́. Kíaríbẹ̀ẹ́ (2022a àti 2023) náà kò ṣàì tọ́ka sí i pé a máa ń kọ orin kete bákan náà níbi ayẹyẹ tí kò jẹ mọ́ ẹ̀sìn ìbílẹ̀.

**Ìṣeré orin agbè/ṣàkàrá**

Orin agbè tí a tún mọ̀ sí orin ṣàkàrá jẹ́ orin tí a máa ń lu àgbè sí. Èso oríṣi igbá kan ni agbè. Ó máa ń ní ẹnu tó jọ ti ìgò, ọrùn agbè a sì máa gùn díẹ̀ torí pé àwọn ohun tí ó ṣe pàtàkì ni àwọn Yorùbá máa ń kó pamọ́ sí inú agbè. Ìdí nìyí tí Yorùbá fi máa ń sọ pé ọ̀rọ̀ agbè ló ń dun ẹlẹ́mu (Kíaríbẹ̀ẹ́, 2022a). Láti gbin agbè tí ó ní ọrùn tó gùn, abẹ́ igi ìgàn-ǹ-gan ni àwọn ará Ilé Gbọ̀nńkáà ní Igbó-Ọrà máa ń gbìn ín sí. Ewé igbá yìí yóò le lọ́ mọ́ igi náà, bí ó bá sì tí ń so ni àwọn èso agbè yóó máa rọ̀ dọ̀ọ̀rọ̀ wálẹ̀ tí wọn yóò sì tún tóbi ní ìwọ̀nba tí wọ́n bá fẹ́. Láti fi agbè tí ó ti gbó sín ìlù orin ṣàkàrá, èsò ìdòrò ni àwọn ọ̀kọrin yìí máa ń sá tí yóó gbẹ, wọn yóò sì sín in mọ́ ara agbè gẹ́lẹ́ bí a ṣe ń sín ṣẹ̀kẹ̀rẹ̀ ṣùgbọ́n wọn kò ní í jẹ́ kí èso náà pọ̀ lára agbè yìí. Wọ́n sì tún le da ọmọ èso ìdòrò náà sínú agbè. Ìlànà yìí ni àwọn Ajóṣàkàrá Ìgbó-Ọrà máa ń gbà láti sín agbè tiwọn. Àwọn Ìlọrin, Ìmia àti Ìluà máa ń sín èsò náà mọ́ ara agbè ni. Lára èsò tí wọ́n tún le sín mọ́ ara agbè ni alùgbáàko/èso igi pórò, ìdò àti èso igi osè. Àwòrán agbè ni a fi hàn ní ìsàlẹ̀ yìí:



**Àwòrán 1**: Agbè tí a kò sín lára



**Àwòrán 2:** Agbè tí a sín lára

Bí agbè bá ṣe kéré sí ni ohùn tí ó máa fọ̀ jáde yóó ṣe le tó. Agbè kékeré, tí ó sì le koko máa ń fọ ohùn tó le koko nígbà tí agbè tó tóbi, tí ó sì kẹnú máa ń fọ ohùn tó dẹ̀ gbẹ̀dẹ̀. Bí ohùn agbè bá dẹ̀ dáradára, èyí yóó mú un rọrùn láti fi agbè náà sọ ọ̀rọ̀ díẹ̀. Irúfẹ́ agbè báyìí ni àwọn ajágbè kà sí ìyá agbè. Èyí tó bá tẹ̀ lé ìyà agbè nínú bí ohun rẹ̀ ṣe dẹ̀ tó ni ẹ̀dà. Àwọn ẹ̀dà wọ̀nyí sì ni wọ́n pọ̀ jùlọ nínú ìlù agbè. Àwọn ni ó máa ń ran ìyá ìlù lọ́wọ́. Nínú àwọn agbè tí ohùn wọn le ni konkolo/pu. Agbè yìí ni ohùn rẹ̀ le jùlọ. Òhun sì ni a kọ́kọ́ máa ń lù tẹ̀ lé agogo nínú ìṣeré agbè tó bá ní agogo nínú. Àwọn omele agbè kan tún wà tí

a pè ní pẹ̀ǹpẹ̀kun. Bí ohùn rẹ̀ ṣe dún ni a ṣe fún un lórúkọ. Òun náà máa ń ran ìwọ́hùn agbè lọ́wọ́ ni.

Òun sì ni àwọn ajágbè tún le já láì dáwọ́ ijó dúró lẹ́yìn ìyá ìlù agbè. Bí ohùn ẹ̀dà bá ti dẹ̀ gbẹ̀dẹ̀ jù, tí ó dẹ̀ ju àwọn ẹgbẹ́ rẹ̀ lọ, ìyá ìlù ni irúfẹ́ ẹ̀dà bẹ́ẹ̀ máa ń gbè, agbèyá-ìlù ni àwọn ọ̀kọrin agbè kan sì ń pè é. Ohun kan gbòógì tó dá agbè/ṣàkàrá àti ṣẹ̀kẹ̀rẹ̀ yà sọ́tọ̀ ni ti ohùn tí kálukú wọn máa ń fọ̀ jáde. Ohùn tí ó dẹ̀ gbẹ̀dẹ̀ ni ṣẹ̀kẹ̀rẹ̀ máa ń fọ̀ jáde torí pé òde ayọ̀ ló máa ń lọ. Yorùbá a tilẹ̀ máa sọ nípa rẹ̀ pé, "Ṣẹ̀kẹ̀rẹ̀ kì í báwọn ròde ìbànújẹ́." Ogun ni ìpìlẹ̀ agbè, ọ̀rọ̀ ogun kò sì rí bí iyán, ogun kò rí bí ẹ̀kọ. Yàtọ̀ sí èyí, àwọn ohun tí a fi máa ń sín ṣẹ̀kẹ̀rẹ̀ yàtọ̀ sí ti agbè; owó ẹyọ àti ìlẹ̀kẹ̀ ni a fi ń sín ṣẹ̀kẹ̀rẹ̀ nígbà tó jẹ́ pé èso pórò tó le koko, ìdò àti àwọn èso mìíràn tó le dáradára ni a fi ń sín ṣàkàrá, kí o le fọ ohùn tó dẹ́rùbani. Tọkùnrin tobìnrin ni ó máa ń ṣe eré agbè, bí kò sì ṣe yọ ọmọdé sílẹ̀ náà ni kò yọ àgbà sílẹ̀. Gbogbo ẹni tí ó bá ti le ṣe eré ipá ni ó le kọ orin, jó agbè, tàkìtì tàbí pa idán nínú orin agbè. Torí náà, orin ipá, tí ó pè fún àmúlò agbára ni orin yìí. Èniyàn tí kò lágbára kò le jó agbè, bákan náà sì ni pé ọ̀lẹ ènìyàn kò le lù ú. Àwọn ajágbè a tilẹ̀ máa lé ọ̀lẹ tí kò le jó tàbí lu ohun èlò ìṣeré náà kúrò lójú agbò bí ó bá fẹ́ ba eré wọn jẹ́.

Oríṣiríṣi kókó ọ̀rọ̀ ni ó máa ń jẹyọ nínú orin agbè. Lára àwọn kókó tí ó wọ́pọ̀ nínú orin agbè ni ọ̀rọ̀/orin ogun, ìmúnilọ́kanle, kóríyá, ọ̀rọ̀ àwàdà, ìjúbà, ìfira-ẹni-hàn, èébú, ọ̀rọ̀ òṣèlú, ọ̀rọ̀ àlùfàǹṣá, ìtàn àtijọ́ àti títú àṣírí ìwà ìbàjẹ́. Ẹni tí ọ̀rọ̀ kì í dùn ni ó le ṣe eré agbè torí pé àwọn ajágbè máa ń kọ orin bú ara wọn lásìkò eré. Bí àwọn ajágbè bá ń lọ sí òde eré, tọmọtìyàwó wọn ni wọ́n máa ń lọ torí náà ni àṣírí àwọn ajágbè kò fi bò. Bí àṣírí wọn kò ṣe bò yìí náà ni àṣírí àwọn ìyàwó wọn àti ọmọ wọn tó jẹ́ oníwà ibi kò bò. Ọ̀rọ̀ orin agbè jẹ́ ọ̀rọ̀ ẹni bá láyà kó wọ̀ ọ́. Ọmọ àlè ni àwọn ọ̀kọrin agbè ka ọmọ wọn tí kò bá mọ eré náà ṣe sí, wọn a sì máà jèrè ọ̀rọ̀ lára irúfẹ́ ẹni bẹ́ẹ̀. Wọ́n ka ìyàwó ilé tí kò bá mọ eré náà ṣe sí òpè ìyàwó tí kò mọ ìṣe àti àṣà àwọn ènìyàn ọkọ rẹ̀. Wọn a máa fi irúfẹ́ àwọn wọ̀nyí náà ṣẹ̀fẹ̀ lágbo eré. Kò sí ipa kankan tí àwọn obìnrin ajágbè náà kò le kó, wọ́n le jẹ́ akọrin, onílù agbè, ajágbè, obìnrin tí agbára rẹ̀ bá ká a náà sì le pa idán tàbí kí ó ta òkìtì ṣùgbọ́n èyí kò wọ́pọ̀. Ṣàṣà ni kókó ọ̀rọ̀ tí kì í jẹyọ nínú orin agbè. Bí a ṣe le fi búni náà ni a le fi ki oríkì ẹni ṣùgbọ́n orin náà ni a sábà máa fi ń ṣe àgbékalẹ̀ èyí. Tọ̀sántòru ni a le jó agbè, kò sì ní èèwọ̀ àkókò kankan láàárín àwọn ọ̀pọ̀lọpọ̀ ajágbè, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé àwọn ènìyàn ìlú Ìdèrè gbà pé lílu agbè ní ọ̀sán gangan le fa ìgbóná, torí náà ni wọ́n ṣe máa ń bọ agbè láti fi tù ú (Àlàbá, 1985).

**Tíọ́rí ìlò-àmì nínú ewì (*Semiotics of poetry*)**

Àwọn onímọ̀ méjì kan tí iṣẹ́ wọn gbajúgbajà nínú ìlò àmì ní àsìkò ayé ọ̀làjú tí a wà yìí ni Ferdinand de Saussure (1857-1913) àti Charles Sanders Peirce (1839-1914) (Cobley & Jansz, 1999). Ọmọ ilẹ̀ Switzerland ni Ferdinand de Saussure, ó sì jẹ́ onímọ̀-èdè nígbà ayé rẹ̀. Ẹ̀wẹ̀, onímọ̀ filọ́sọ́fì, ọmọ ilẹ̀ America ni Charles Sanders Peirce (Sebeok, 2001). Àwọn méjèèjì ló fi ojú ìlànà tí wọ́n nímọ̀ nípa rẹ̀ wo ìlò àmì àti ìtumọ̀ rẹ̀ (Ògúndèjì, 1988). Ojú èdè ni Ferdinand de Saussure fi wo ìlò àmì torí náà ó gbà pé ìwọ̀fún ni àwọn lẹ́tà èdè gbogbo, ìtumọ̀ wọn kò níkan an ṣe pẹ̀lú ohun tí wọn dúró fún nínú èdè. Fún ìdí èyí, tíọ́rì ìlò àmì Ferdinand de Saussure dúró lé àmì (*signifier*) àti ìtumọ̀ àmì (*signified*). Saussure wá jẹ́ kó di mímọ̀ pé akitiyan láti ya àwọn ohun méjì yìí sọ́tọ̀ máa sọ ìtumọ̀ àmì nù ni. Charles Sanders Peirce ní tirẹ̀ gbà pé ìlò àmì dúró lé orin ohun mẹ́tàlọ́kan kan. Àwọn ohun náà ni *representamen*, *object* àti *interpretant*.

Gẹ́gẹ́ bí àlàyé Eco (1976), *representamen* ni a le fi wé ọkọ̀ àmì. *Interpretant* ni a le fi wé òfin tó de ìlò àmì, ohun tó sọ fúnni pé ìtumọ̀ báyìí pàtó ni àmì le ní nígbà tí a bá fi ojú kan wò ó (Eco, 1976), nígbà tí *object* jẹ́ ohun tí àmì ń tọ́ka sí. Ògúndèjì (1988) tilẹ̀ fi tíọ́rì àmì àwọn méjèèjì wéra. Ó sọ pé *representamen* dúró gẹ́gẹ́ bí òfin tó de ìlò àmì, *object* dúró gẹ́gẹ́ bí ọkọ̀ àmì (ìrísí àmì) nígbà tí *interpretant* dúró gẹ́gẹ́ bí ohun tí àmì túmọ̀ sí. Ó wá ní ọkọ̀ àmì àti ohun tí àmì túmọ̀ sí kò le gbé òye ìtumọ̀ àmì yọ láì fi ti òfin àmì ṣe. Ohun tí Ògúndèjì (1988) ṣe yìí jẹ́ kí á rí *object* ti inú tíọ́rì àmì Charles Sanders Peirce gẹ́gẹ́ bíi

*signifier* ti inú tíọ́rí ìlò àmì Ferdinand de Saussure, tí a sì rí *interpretant* gẹ́gẹ́ bíi *signified* nígbà tí a rí *representamen* gẹ́gẹ́ bí òfin tí Ferdinand de Saussure pè ní ìwọ̀fún nínú àṣà àti èdè, èyí tó gbé ìtumọ̀ àmì dúró, tí a kò sì le yà lára *signifier* àti *signified*.

Torí pé ewì ní ìlànà ìlò-èdè tirẹ̀, èyí tó yàtọ̀ sí ìlò-èdè ojojúmọ́ ni àwọn onímọ̀ bíi Eco (1976) àti Ògúndèjì (1988) fi gbà pé ìlò àmì wọ́pọ̀ nínú èdè ewì ju èdè ṣákálá lásán lọ. Àbùdá tí èdè ewì ní yìí ló mú Riffaterre (1978) gbà pé ó yẹ kí ewì ní ìlànà tirẹ̀ tí à máa tẹ̀ lé láti ṣe àgbéyẹ̀wò àwọn ìlò àmì inú rẹ̀. Èyí sì mú un dábàá tíọ́rì tí ó pè ní *Semiotics of Poetry,* èyí tí a pè ní 'Tíọ́rì ìlò àmì nínú ewì.' Riffaterre (1978) ṣàlàyé pé a máa ń lo àwọn ọ̀rọ̀ ìkàsì, tí a patì, tí a kì í sì í fi bẹ́ẹ̀ lò nínú èdè ojojúmọ́ nínú ewì. Riffaterre sọ pé, kí á tó le gbọ́ èdè ewì yé yéké, a nílò láti wo ìtumọ̀ ìdúrófún (ìtumọ̀ eréfèé) àti ti ìjásí (ìjìnlẹ̀) àwọn àmì tí a lò nínú rẹ̀.

Riffaterre tún ṣe é ní àlàyé pé gbólóhùn kékeré tí kò le ni a máa ń pa láwọ̀ dà di ohun tó le koko, tó sì jinlẹ̀ nínú ewì. Ó wá sọ pé láti mọ ìtumọ̀ tí ìpèdè ewì kan ní, a ní láti ṣàwárí ọ̀rọ̀/fọ́nrán ìpìlẹ̀ "*semes*" tí a pa láwọ̀ dà di èdè ewì (Riffaterre, 1978: 23). Riffaterre ní láti pa fọ́nrán láwọ̀ dà nínú ewì, a le fẹ irúfẹ́ fọ́nrán bẹ́ẹ̀ lójú, a sì le yí i dà. Onímọ̀ yìí tún sọ pé láti wádìí ìtumọ̀ ìjìnlẹ̀ gbólóhùn ewì, títọ́ka sí àwọn ohun mìíràn tí ìpèdè tàbí fọ́nrán ewì náà jọ le ràn wá lọ́wọ́. Onímọ̀ yìí tún jẹ́ ká mọ̀ pé fọ́nrán inú ewì kan ṣoṣo le dúró fún ohun tó pọ̀. Ìtumọ̀ irúfẹ́ àwọn àmì onítumọ̀ pọ́nna báyìí yóò sì ní í ṣe pẹ̀lú àyè tí a ti lò ó. Riffaterre tún fi kún ọ̀rọ̀ rẹ̀ pé àwọn àmì tí kò ní ìtumọ̀ nínú èdè ojojúmọ́ máa ń ní ìtumọ̀ nínú ewì.

Bí a bá wo gbogbo ohun tí Riffaterre sọ wọ̀nyí, ó bá àwọn ewì alohùn Yorùbá gẹ́gẹ́ bí orin agbè mu ṣùgbọ́n àìmọye ni àwọn ohun mìíràn tó le dúró gẹ́gẹ́ bí àmì nínú ewì ìbílẹ̀ Yorùbá tí Riffaterre kò mẹ́nuba torí pé onímọ̀ náà kò mọ̀ nípa àṣà Yorùbá. Torí náà, ohun ìlànà lásán ni a fi tíọ́rì ìlò àmi nínú ewì Riffaterre yìí ṣe, a kò fojú fo àwọn àmì tó jẹ́ mọ́ àṣà Yorùbá, èyí tó jẹyọ nínú ìṣeré orin agbè tí a tú palẹ̀ yìí yálà àmì bẹ́ẹ̀ jẹ́ mọ́ ọ̀rọ̀ ẹnu tàbí ó jẹ mọ́ ìṣe pọ́nńbélé.

**Bí àwọn ajágbè ṣe máa ń pe ara wọn níjà**

Gẹ́gẹ́ bí a ti ṣe sọ ṣíwájú, orin agbaja àti kóríyá ni orin agbè/ṣàkàrá. Nígbà tí eré orin ṣàkàrá bá fẹ́ wáyé, àwọn òṣèré tí máa ń gbáradì gan-an. Nínú àlàyé tí Bàbá Mátíù Ọ̀jẹ́ẹ̀lù (Atakóró), tí wọ́n jẹ́ olórí ẹgbẹ́ eléré agbè ní ìlú Ilùà, ní Ìjọba Ìbílẹ̀ Kájọlà, Òkè-Ògùn, Ìpílẹ̀ Ọ̀yọ́ ṣe, kí eré tó bẹ̀rẹ̀ ni ìpèníjà tí máa ń wà fún ajágbè. Ohun tó jẹ́ kí èyí rí bẹ́ẹ̀ ni pé àwọn ìkà ènìyàn kan máa ń fẹ́ láti dán àwọn òṣèré náà wò nígbà tí wọ́n bá ń ṣe eré tàbí pa idán. Torí náà, kí eré tó bẹ̀rẹ̀ ni ajágbè tó bá fẹ́ ṣe àṣeyọrí nínú ìṣreré ti gbọ́dọ̀ múra sílẹ̀ de ìpèníjà yòówù tí ó le jẹyọ nínú eré. Mátíù Ọ̀jẹ́ẹ̀lù (Atakóró) fi kún ọ̀rọ̀ rẹ̀ pé kì í ṣe ìgbáradì òògùn nìkan ni àwọn ti máa ń ṣe, ìgbáradì nínú gbogbo ìṣeré àwọn ni àwọn máa ń ṣe kí wọ́n má baà dojú ti ẹgbẹ́ wọn bí eré náà bá ń lọ lọ́wọ́. Láti mú kí ìṣeré wọn lọ bí ó ti yẹ, Mátíù Ọ̀jẹ́ẹ̀lù (Atakóró) ṣe àlàyé pé àwọn máa ń pe ara àwọn níjà láti ṣe ohun tó tọ́ lásìkò eré. Gẹ́gẹ́ bí ìwádìí wa nípa ìṣeré orin agbè ṣe fi hàn, àwọn ọ̀nà wọ̀nyí ni àwọn ajágbè máa ń gba pe ara wọn níjà nínú eré agbè; ìpera-ẹni-níjà nínú agbè lílù, orin kíkọ, ìṣeré ojúlówó, ijó jíjó/òkìtì títa/idán pípa fún ìdárayá, níní ìgboyà àti ìpera-ẹni-níjà nípa àmúlò òògùn ìkà fún ogun jíjà.

**Ìpera-ẹni-níjà nínú agbè lílù**

Agbè lílù mú àwọn ìṣòro kan lọ́wọ́, èyí ló fà á ti kì í fi i ṣe ohun tí ọ̀gbẹ̀rì kan le ṣàdédé gbé pé òun máa lù. Ní àkọ́kọ́, agbè tó le dáradára ni wọ́n fi máa ń sín ní ṣàkàrá. Bí agbè bá ṣe le tó ni yóó ṣe fọ ohun tó já gaara tó. Irúfẹ́ agbè líle yìí máa ń ta àwọn tó ń lù ú lọ́wọ́, lọ́pọ̀ ìgbà bí ó bá jẹ́ àwọn agbè tí a kò sín nǹkan kan mọ́ lára. Yàtọ̀ sí èyí, èsò tó le koko ju owó ẹyọ tàbí ìlẹ̀kẹ̀ tí a fi ń sín ṣẹ̀kẹ̀rẹ̀ lọ ni àwọn ajágbè fi máa ń sín ṣàkàrá. Èyí náà a máa tani lọ́wọ́ bí a bá ti ń lù ú kárakára. Torí náà, ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn onílù agbè ló máa ń yan agbè tí kò le púpọ̀ nígbà tí wọ́n bá fẹ́ bẹ̀rẹ̀ eré.




**Àwórán 3:** Àwọn onílù agbè ń yan agbè tí wọ́n le lù

Wọn yóò sì máa dán ohùn agbè tí wọ́n yàn náà wò bóyá ó le fọ ohùn tí onílù náà máa ń lù. Àwọn agbè tó bá ti le jù báyìí, ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn onílù ló máa ń kọ̀ ọ́ sílẹ̀. Ògá ni àwọn onílù yòókù máa ń ka òṣèré tó bá lu irúfẹ́ agbè bẹ́ẹ̀ dáradára fún ìgbà pípẹ́ sí. Agogo ni àwọn onílù agbè kọ́kọ́ máa ń lù bí eré bá ti fẹ́ bẹ̀rẹ̀. Ohùn agogo yìí ni ohùn àwọn agbè yóò tẹ̀ lé. Gbogbo agbè ni olórí ọ̀kọrin agbè gbọ́dọ̀ kíyè sí pé ó ti fọhùn kí orin tó bẹ̀rẹ̀. Láti bẹ̀rẹ̀ orin báyìí, irúfẹ́ orin ìsàlẹ̀ yìí ni ọ̀kọrin agbè máa ń kọ ní inú ìṣeré agbè ní ìlú Igbó-Ọrà láti pe àwọn ọ̀kọrin níjà:

Lílé: Agogo ń ró ooooooo
Àbí ò ró ò
Kèǹgbè ooooooo
Ègbè: Agogo ń ró ooooooo
Àbí ò ró ò?
Kèǹgbè ooooooo

Nínú orin òkè yìí, ọ̀kọrin jẹ́ kí á mọ̀ pé agogo ti ń dún kíkankíkan. Ohùn rẹ̀ náà sì ṣe rẹ́gí. Ọ̀kọrin fẹ́ láti fi ẹsẹ̀ ríró agogo yìí múlẹ̀ ni ó tún fi béèrè pé “Àbí ò ró ò?” A máa rí i pé “Kèǹgbè ooooooo” ni gbólóhùn tí ọ̀kọrin fi parí lílé orin yìí. Bí a bá kíyè sí ìpèdè náà gẹ́gẹ́ bí ọ̀kọrin ṣe lò ó yìí, níṣe ló dàbí ẹni wí pé ọ̀kọrin fi kèǹgbè sí ipò òsùnsùn afọ̀ ìbéèrè rẹ̀ “Àbí ò ró ò?; Kèǹgbè ooooooo.” Nínú àṣà orin kíkọ láàrín àwọn Yorùbá, wọ́n máa ń fi orúkọ ìlù tí onílù kan ń lù pe onílù náà. Wọ́n sì le fi orúkọ ìlù tí ó ń lù náà sí ẹ̀yìn orúkọ rẹ̀ gẹ́gẹ́ bí Orlando Ọ̀wọ̀ ṣe máa ń pe onílù rẹ̀ kan ní Adé Kongà. Kóńgà kò sí lára orúkọ onílù náà ṣùgbọ́n a fi kún orúkọ rẹ̀ láti fi ṣe ìyàtọ̀ láàárín rẹ̀ àti ẹlòmíràn tí ó tún le máa jẹ́ Adé nínú ọ̀wọ́ eléré yìí. Bákan náà, ó tún jẹ́ àpọ́nlé fún onílù náà. Irúfẹ́ ohun yìí ni ọ̀kọrin agbè ṣe níbí nígbà tó pe àwọn onílù agbè rẹ̀ ní “Kèǹgbè.”

Orúkọ mìíràn fún agbè ni kèǹgbè, akèrègbè tàbí kèrègbè. Ìlò àmì nípa ìfohunpènìyàn ni ọ̀kọ̀rin lò ní ibi. Torí náà, àwọn onílù agbè ni kèǹgbè tí ọ̀kọrin lò nínú gbólóhùn yìí dúró fún. Ìpèníjà ní gbólóhùn yìí jẹ́ fún wọn pé bí agogo ṣe ń ró kíkankíkan ni kí àwọn náà jẹ́ kí kèǹgbè/agbè/ṣàkàrá tí wọ́n ń lù náà ó máa dún. A tún le sọ pé ọ̀kọrin tún pe àwọn elégbè rẹ̀ níja láti jẹ́ kí àwọn náà gbe orin gẹ́lẹ́ bí agogo àti kèǹgbè ṣe ń dún.

A tún le rí àpẹẹrẹ ìpera-ẹni-níjà nínú agbè lílù nígbà tí ọ̀kọrin agbè bá pe àwọn onílù agbè sí àkíyèsí láti lu irúfẹ́ bátànì ìlù agbè kan. Àpẹẹrẹ kan nìyí:

Lílé: Là á mẹ́taaaa
Là á mẹ́ta
Tayélolú là á mẹ́ta ò
Ègbè: Kó lè ró bí àgogo
Lílé: Eléjìrẹ́ là á mẹ́ta ò
Ègbè: Kó lè ró bí àgogo

Nínú orin agbè yìí, ọ̀kọrin pe àwọn onílù agbè níjà láti la agbè tí wọn ń lù sí mẹ́ta kí ó le ró/dún bí agogo. Yorùbá bọ̀ wọ́n ní, "Kogókogó ni ohùn agogo, dùgbẹ̀dùgbẹ̀ lohùn akèrègbè." Ohun tí òwe yìí ń tọ́ka sí ni pé agogo máa ń dún dáradára ju akèrègbè/agbè lọ, ohun rẹ̀ sì máa ń là kooro ju ti agbè tí kì í là kooro ṣùgbọ́n tí ó kàn máa ń dún dùgbẹ̀dùgbẹ̀ lọ. Nínú orin yìí, ọ̀kọrin wa pe onílù agbè níjà pé kí ó la ohùn agbè mẹ́tà. Líla ohùn agbè mẹ́ta yìí jẹ́ àmì kan tó dúró fún bátànì agbè lílù onídíndún-nísọ̀rí-mẹ́ta. Èyí ni pé kí á lu agbè láti dún tẹ̀léra ní ẹ̀ẹ̀mẹta. Kì í ṣe agbè nìkan ni a le lù kí ó dún ní ìsọ̀rí mẹ́ta tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ. Nínú ìlù bàtá ni bátànì yìí wọ́pọ̀ sí, èyí ni ó sì máa ń mú kó rọrùn fún ajóbàtá láti já a ní ìgbà mẹ́ta. Bí èyí bá rí bẹ́ẹ̀, a jẹ́ pé àmì ìpè fún lílu agbè oníbátànì ìpele mẹ́ta ni gbólóhùn "Là á mẹ́taaaa" tí ọ̀kọrin fi pe onílù agbè náà níjà jẹ́. Ọ̀kọrin fi kún un pé nígbà tí onílù bá tó la agbè náà mẹ́ta ni agbè tó ń lù yóò tó dún dáradára gẹ́gẹ́ bí agogo ṣe ń dún.

**Ìpera-ẹni-níjà nípa orin kíkọ**

Ọ̀nà méjì ni a le pín orin kíkọ sí nínú eré agbè; orin lílé àti orin gbígbè. Àwọn olórin ni awakọ̀ eré, àwọn sì ni wọ́n máa ń sọ èyí tó kàn nínú eré. Orin tí wọ́n ń kọ náà ni wọ́n máa ń lò láti ṣe gbogbo èyí. Àwọn olórin ni ó máa ń ṣe iṣẹ́ ìpèníjà jù nínú eré agbè. Àwọn náà ni ó máa ń pe ọmọ ẹgbẹ́ kọ̀ọ̀kan níjà nípa ìṣeré tí ó ń ṣe. Bí wọ́n ṣe ń pe àwọn onílù, oníjó, olókìtì àti òǹwòran níjà ni wọ́n máa ń pe ara wọn níjà. Ìpèníjà yìí á wá jẹ́ láàárín ọ̀gá olórin àti àwọn elégbè rẹ̀. Ẹ jẹ́ kí á wo àpẹẹrẹ yìí:

Lílé: Oníjó yìí o
Ègbè: Elègbè o
Lílé: Orin lónìí o
Ègbè: Elègbè o
Lílé: Àwọn èèyèn mi ò gberin bí àti...
Ègbè: Àwọn èèyàn mi ò kọrin bí àtìjọ́ mọ́
Lílé: Àwọn èèyàn mi ò gberin bí ati...
Ègbè: Àwọn èèyàn mi ò kọrin bí àtìjọ́ mọ́ o

Bí a bá wo orin òkè yìí, ọ̀kọrin tí ó jẹ́ alérin pe àwọn oníjó nígbà tí ó sọ pé "Oníjó yìí o." Àwọn elégbè náà dá a lóhùn nígbà tí wọ́n sọ pé "Elegbè o." Ohun tí èyí fi hàn ni pé àwọn elégbè ti mọ̀ pé ọ̀kọrin fẹ́ láti dárúkọ àwọn náà ṣùgbọ́n bátànì ìwọ́hùn orin yìí kò gbà á láwè láti ṣe bẹ́ẹ̀ nínú gbólóhùn tó fi kọ́kọ́ lé orin náà. Ẹ̀wẹ̀, nínú àwọn ọmọ ẹgbẹ́ olórin agbè yìí, àwọn "elègbè" tí àwọn elégbè dárúkọ yìí nìkan ló le bá ìwéhùn irúfẹ́ orin agbè náà mu jùlọ nínú ìlà yẹn. "Olókìtì" náà le bá a mu ṣùgbọ́n kò le bá a mu tó "elègbè" tí elégbè náà lò láti fi gbe orin yìí. Bákan náà, "ajágbè" náà le bá ìwéhùn yan mu ṣùgbọ́n èyí já sí pé a ṣe àwítúnwí ìtumọ̀ fún "oníjó" tí ọ̀kọrin kọ́kọ́ lò náà ni. Ìdí ni pé "oníjó" náà ni "ajágbè" túmọ̀ sí. Bí a bá wo ìlà èlé orin tó tẹ̀ lé ègbè yìí ("Orin lónìí o") àti ègbè rẹ̀ ("Elègbè o"), tí kò yàtọ̀ sí ti àkọ́kọ́, a ó rí i pé ọ̀kọrin/alérin jẹ́ kí á mọ̀ gbangba níbí pé àwọn "elègbè" ni ó fẹ́ láti dojú afọ̀ náà kọ́.

Ní ìtẹ̀síwájú èlé àti ègbè orin níbi tí ọ̀kọrin ti sọ pé “Àwọn èèyèn mi ò gberin bí àti...,” tí àwọn elégbè sì bí a gbe orin náà nígbà tí wọ́n sọ pé “Àwọn èèyàn mi ò kọrin bí àtìjọ́ mọ́” ni ó tó hàn gbangba pé ìfànfà ìpera-ẹni-níjà láàárín alérin àti àwọn elégbè rẹ̀ ni kókó ọ̀rọ̀ inú orin yìí, alérin kàn lo “Oníjó yìí o” tó bẹ̀rẹ̀ orin náà kí ó le bá ìwọ́hùn/ìwéhùn orin tó ń kọ náà mu ni. Èyí ló sì mú kí àwọn elégbè tí ó ti mọ ibi tí ó fẹ́ yà sí ní pàtó yára bá a dárúkọ ọ̀wọ́ ọ̀ṣèré tó fẹ́ fi orin náà bá wí. Bí àwọn elégbè ṣe ṣe yìí fi hàn gẹ́lẹ́ pé wọ́n mọ ìlànà ìṣeré wọn dájú. Torí náà, àmì ìmọra-ẹni-dájú àti ìmọ̀-ọ́nṣe kíkún ni èyí jẹ́ nínú ìṣeré orin agbè.

Níṣe ni àwọn ọ̀kọrin/olórin pe ara wọn níjà níbí. Alérin ló kọ́kọ́ bẹ̀rẹ̀ ìpèníjà yìí nígbà tó sọ pé “Àwọn èèyàn mi ò gberin bí àti...” tí àwọn elégbè sì bá a parí gbólóhùn rẹ̀ ṣùgbọ́n tó jẹ́ pé èsì gbólóhùn tí kò parí náà gẹ́lẹ́ ni wọ́n fún un nígbà tí wọ́n dáhùn pé “Àwọn èèyàn mi ò kọrin bí àtìjọ́ mọ́.” Nínú ìṣeré ìbílẹ̀, èébú ńlá ni bí a bá sọ pé àwọn agberin kò gberin bí àwọn ará ìṣíwájú ṣe máa ń gbè é. Èyí kò dùn mọ́ àwọn elégbè náà nínú, wọ́n yára jẹ́ kí alérin náà mọ̀ pé òun ló fà á tí àwọn kò fi gbe orin náà dáradára bí àwọn elégbè àtijọ́. Wọ́n sọ pé àwọn ènìyàn àwọn, tí ó ń tọ́ka sí alérin náà kò lé orin bí àwọn ará ìṣíwájú ṣe máa ń lé e fún àwọn elégbè wọn. Ṣé Yorùbá bọ̀, wọ́n ní “Orin tí Ẹ̀lúkú bá dá ni ọmọ rẹ̀ ń gbè.” Bí ó ṣe jẹ́ èébú fún àwọn elégbè pé wọn ò gbe orin bí àtijọ́ mọ́ náà ni ó jẹ́ èébú ńlá fún ọ̀kọrin pàápàá pé òun náà kò kọ orin bí àtijọ́ mọ́. Ìpèníjà láti kọ orin bí ó ti yẹ, àti láti gbè é bí ó ṣe tọ́ ni orin yìí jẹ́ nínú eré agbè ṣíṣe. Torí náà, àmì kíkọ àti gbígbè orin agbè bí ó ti yẹ ni irúfẹ́ ìpera-ẹni-níjà báyìí dúró fún nínú ìṣeré orin agbè.

**Ìpera-ẹni-níjà nípa ojúlówó ìṣeré**

Nígbà tí àwọn ajágbè/olórin agbè bá pe ara wọn níjà nípa ojúlówó ìṣeré, ohun tí ó ń tọ́ka sí ni pé gbogbo ìṣeré wọn pátá ni wọ́n fẹ́ kí wọ́n ṣe bó ṣe yẹ, yálà orin agbè kíkọ, ìlù agbè lílù, òkìtì títa àti ijí jíjó. Ẹ jẹ́ kí á wo àpẹẹrẹ ìsàlẹ̀ yìí:

Lílé: A ó ṣorò o
A ó ṣorò Ilé
Ègbè: Òṣooroṣóooròòò
Lílé: A ó ṣorò o
A ó ṣorò Ilé
Ègbè: Òṣooroṣóooròòò

Orin ìṣíde eré agbè ni orin òkè yẹn jẹ́ (Kíaríbẹ̀ẹ́, 2023). Àwọn ajágbè Igbó-Ọrà máa ń fi orin náà ṣíde eré wọn ni. Àwọn ajágbè yìí ka eré agbè sí ogún-ìbí wọn, wọ́n sì gbà pé àṣà àti orò ilé Gbọ̀nńkáà tí àwọn ti ṣẹ̀ wá láti Ọ̀yọ́ Ilé ni. Torí náà, wọ́n máa ń fi orin òkè yẹn rán ara wọn létí bí eré agbè ṣe jẹ́ sí ìran wọn. Èyí sì jẹ́ ohun ìpera-ẹni-níjà pàtàkì láti ṣe ojúlówó eré, kí wọ́n sì fi ara ṣe eré náà. Ọmọ àlè ni àwọn ènìyàn yìí ka ọmọ bíbí ilé wọn tí kò le ṣe eré agbè bó ṣe yẹ sí, wọn a sì máa tọ́ka sí ẹni tí ó bá ṣe eré bó ṣe yẹ gẹ́gẹ́ bí ọmọ ọkọ ilé wọn. Wọn a máa kọ ọ́ lórin báyìí:

Lílé: Eléyìí ọmọ wa
Ègbè: Èyí ọmọ wa
Lílé: Eléyìí ọmọ wa
Ègbè: Èyí ọmọ wa

Ohun tí orin yìí dúró fún ni àmì pàtàkì láti fi ọmọ ọkọ hàn. Torí pé a le fi ajágbè hàn bóyá ọmọ ọkọ ni tàbí ọmọ àlè ní gbàngba. Gbogbo ọmọ Ilé Gbọ́nńkáà/Ajọ́ṣàkàrá, Òkè-Ìṣẹrin, Igbó-Ọrà ni ó máa ń múra láti ṣe ojúlówó eré kí á má ba à pè wọ́n ní ọmọ àlè lásìkò eré. Àpẹẹrẹ orin tí a fi le fi ọmọ àlè hàn ni àyídà orin agbè òkè yẹn:

Lílé: Eléyìí ọmọ wọn
Ègbè: Èyí ọmọ wọn
Lílé: Eléyìí ọmọ wọn
Ègbè: Èyí ọmọ wọn

Bí àwọn àbúrò baba ẹni bá ti ń pè ènìyàn ní ọmọ wọn, tí wọn kò pè é ní ọmọ wa, àmì ìtàdànù pàtàkì ni nínú ìṣeré orin àgbè. Ó tún jẹ́ àmì àfihàn ìṣeré tí a kò tẹ́wọ́ gbà.

Nígbà mìíràn, àwọn ajágbè le pè fún ojúlówó eré nípa bíbéèrè fún ẹni tó le jó ijó tàbí ta òkìtì kan ní pàtó. Ẹ jẹ́ kí á wo àpẹẹrẹ ìsàlẹ̀ yìí:

Líle: Olóbìírípobírí
Ègbè: Òní la ó maláré
Líle: Olóbìírípobírí
Ègbè: Òní la ó maláré...

Bí a bá wo àlàyé Kiáríbẹ̀ẹ́ (2023), oríṣi ijó agbè kan ni olóbìírípobírí. Torí pé ajágbè tí ó bá ń jó ijó yìí máa ń pòòyì rànhìn ni a ṣe pe ijó náà ní orúkọ yìí. Nígbà tí àwọn ọ̀kọrin bá fẹ́ láti ṣe ojúlówó eré, wọn a máa jó ijó náà, wọn a sì máa béèrè fún ajágbè tí ó le ṣe irúfẹ́ eré ijó yìí. Torí náà ni àwọn elégbè fi là á mọ́lẹ̀ gbangba pé òní ni àwọn máa mọ ojúlówó ẹni tí ó le jó ijó olóbìírípobírí. Ẹnikẹ́ni tí ó bá le jó ijó náà ni àwọn ajágbè máa gbà sí ojúlówó eléré/aláré agbè. Òṣùwọ̀n tí a fi ń mọ ojúlówó òṣèré ni àmì/àrokò pàtàkì tí ijó olóbìírípobírí ń pa nínú ìṣeré orin agbè. Ó sì tún dúró gẹ́gẹ́ bí ìpèníjà fún ojúlówó ijó agbè.

Bákan náà ni ó jẹ́ pé àwọn ọ̀kọrin agbè máa ń pe ara wọn àti àwọn òṣèré yòókù níjà bí wọ́n bá ṣe àkíyèsí pé eré náà ti ṣẹ̀ṣẹ̀ ń di ọwọ́ ààrẹ̀. Èyí wà láti rán ara wọn létí pé akọ igi wọn kò gbọdọ̀ ṣoje. Láti ṣe eléyìí, àwọn ajágbè máa ń kọ orin ìsàlẹ̀ yìí:

Lílé: Ajágbè àbí ẹ sùn ni?
Ègbè: Oorun wẹ̀!
Oorun báwo!
Lílé: Ajágbè àbí ẹ sùn ni ò?
Ègbè: Oorun wẹ̀!
Oorun báwo!

Nínú orin agbè òkè yẹn, alérin pe àwọn ajágbè níjà nítorí pé ó ṣe àkíyèsí pé ó dàbí ẹni tí ó ti ń rẹ̀ wọ́n nígbà tí ó sọ pé, “Ajágbè àbí ẹ sùn ni?” Nígbà tí ènìyàn kò bá ta kebékébé mọ́ bí ó ṣe ń ta nígbà tí kò tí ì rẹ̀ é, ohun tó dájú ni pé ó ti ń rẹ olúwa rẹ̀. Kì í ṣe ìgbà tí ènìyàn bá dijú, tí kó sì mọ ohun tí ó ń ṣẹlẹ̀ sí i mọ́ nìkan ni Yorùbá máa ń gbà pé ènìyàn sùn. Wọn a máa fi oorun júwe ẹni tí ó ti gbàgbéra náà. Ìdí nìyí tí wọ́n fi máa ń dá a láṣà pé “Àbí o sùn ni?” Ẹni tí a bá béèrè irúfẹ́ ìbéèrè yìí lọ́wọ́ rẹ̀, tí onítọ̀hún kò sì sùn lóòótọ́, bó bá jẹ́ pé ẹni tó mésì ọ̀rọ̀ dáradára ni, ohun tí olúwa rẹ̀ yóò fi dáhùn ni pé, “Oorun wẹ̀ níwájú adájọ́!” Ohun tí èyí ń tọ́ka sí ni pé ẹni tí à ń bá wí náà kò sùn rárá, ó kàn le pirọrọ torí pé ó ti ń rẹ̀ ẹ́. Nígbà tí alérin agbè bá wá bi àwọn ajágbè léèrè, èyí tí a le pè ní gbogbo àwọn eléré agbè tí ó wà níbi ìṣeré náà pé ṣé wọ́n ti sùn ni, èsì tí wọn fi máa ń dáhùn ni “Oorun wẹ̀!; Oorun báwo!” gẹ́gẹ́ bí ó ti jẹyọ nínú orin ìtara-ẹni-jí àti ìpera-ẹni-níjà òkè yẹn. “Oorun” tí a lò nínú orin ìpèníjà/ìtanijí òkè yìí dúró fún kí ó rẹni tàbí kí ènìyàn tí máa kááàrẹ̀ torí pé ó ti ń ṣe iṣẹ́ láti àárọ̀, kì í ṣe pé oorun tí a máa ń sùn nígbà tí a bá dijú wa, tí a kò sì mọ ohun tí ó ń ṣẹlẹ̀ mọ́.

**Ìpera-ẹni-níjà nípa ijó jíjó/òkìtì títa àti idán pípa fún ìdárayá**

A ti sọ̀rọ̀ díẹ̀ nípa bí àwọn ajágbè ṣe máa ń pe ara wọn níjà nínú ijó nígbà tí a sọ̀rọ̀ lórí bí wọ́n ṣe máa ń pe ara wọn níjà láti ṣe eré ojúlówó. Ohun tó jẹ́ kí àlàyé yìí wọnú ara wọn díẹ̀ báyìí ni pé ara eré tí àwọn ajágbè máa ń ṣe ni ijó náà wà. Láti fi ìdí èyí múlẹ̀, Ògúndèjì (1979) sọ pé oníjó kan tí gbogbo òwòran orin agbè máa ń fẹ́ láti wò ni Ìyàwó Agbè. Èyí ni ajágbè tí ó máa ń múra bí obìnrin, tí yóò sì máa jó, tí yóò máa rèdí gẹ́lẹ́ bí àwọn obìnrin ṣe máa ń jó. Àpẹẹrẹ mìíràn lórí bí àwọn ọ̀kọrin agbè ṣe máa ń pe ara wọn níjà nínú ijó jíjó ní bí wọ́n ṣe máa ń béèrè bóyá ajágbè le jó irúfẹ́ ijó kan gẹ́gẹ́ bí ó ṣe hàn nínú orin ìsàlẹ̀ yìí:

Lílé: Ṣo ó leè jó oòèà?
Ègbè: O ò le jó oòèa
Lílé: Ṣo ó leè jó bíi Láǹgabà ò?
Ègbè: O ò le jó bíi Láǹgabà ò
Lílé: Ṣo ó leè jó bí Olóhùn-agbè ò?
Ègbè: O ò le jó bí Olóhùn-agbè ò

Bí a bá wo orin òkè yẹn, a máa rí i pé ìpèníjà tààrà ni. Ní àkọ́kọ́, gbólóhùn ìbéèrè tó fẹ́ láti mọ̀ bóyá ajágbè kápá láti jó ni. Ajágbè/oníjó-agbè ni wúrẹ̀n arọ́pò orúkọ ẹnikejì ẹyọ “o”, tí ó ràn méyìn láti sọ fáwẹ̀lì “é” tó jẹ yọ nínú ìhun ìpìlẹ̀ wúrẹ̀n ìbéèrè “ṣé” di bí ara rẹ̀, ń tọ́ka sí. Àjágbè yìí náà sì ni àwọn elégbè tọ́ka sí nígbà tí àwọn náà pè é níjà pé kò le jó nínú ìlà kejì orin agbè yìí. Nínú gbólóhùn kẹta ni alérin ti tẹ̀ síwájú nínú gbólóhùn ìbéèrè onípèníjà náà nípa bíbéèrè pé ǹjẹ́ ajágbè le jó bíi Láǹgabà. Àwọn elégbè orin náà kín alérin lẹ́yìn nínú ìpèníjà yìí nígbà tí wọ́n sọ pé “O ò le jó bíi Láǹgabà ò.” Èyí tọ́ka sí i pé ajágbè náà kò le jó bíi Láǹgabà. Alérin tún ìbéèrè onípèníjà yìí béèrè nígbà tó tún bi ajágbà pé “Ṣo ó leè jó bí Olóhùn-agbè ò?” Àwọn elégbè náà kò sì ta ko èrò alérin yìí, èyí fi hàn nínú gbólóhùn ègbè tí wọ́n ti sọ pé, “O ò le jó bí Olóhùn-agbè ò.”

Ó yẹ kí á béèrè pé báwo ni ti Láǹgabà àti Olóhùn-agbè ti ẹ jẹ́ nínú ìṣeré orin agbè. Ohun tí ìtàn ìṣeré agbè ní ìlú Igbó-Ọrà fi múlẹ̀ ni pé, ajágbè ayé àtijọ́ ni Láǹgabà. Bàbá Tìámíyù Òjó tí wọ́n jẹ́ Baálé Ilé Ajóṣàkàrá, Òkè-Ìṣẹrin, Igbó-Ọrà nínú ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò tí a ṣe fún wọn ní ọjọ́ kejìlélógún, oṣù keje, ọdún 2018 (22/07/2018) ṣe àlàyé pé, Láǹgabà jẹ́ ajágbè tí ìtàn kò tí ì tọ́ka sí ajágbè mìíràn tó rí bíi tirẹ̀ rí. Bí Láǹgabà bá ń jó, ó máa ń fi ẹsẹ̀ wú ilẹ̀, kò sì sí bí ilẹ̀ náà ṣe le tó tí ijó Láǹgabà kò ní i sọ ọ́ di rírọ̀. Torí pé àwọn ajágbè kò rí irúfẹ́ òṣèré agbè yìí rí ni wọ́n ṣe máa ń lo ijó rẹ̀ gẹ́gẹ́ bí òṣùwọ̀n tí a le fi wọn ijó agbè tó dára púpọ̀. Gbogbo ajágbè ni ó máa fẹ́ jó gẹ́gẹ́ bíi rẹ̀. Bí wọ́n bá kọrin láti fi pe oníjó níjà pé kí ó jó bíi Láǹgabà, ohun tí wọn ń tọ́ka sí fún irúfẹ́ ajágbè bẹ́ẹ̀ ni pé kó jó ojúlówó ijó agbè. Torí náà, àròkò ijó agbè tó dára gan-an ni Láǹgabà máa ń pa nínú ìṣeré orin agbè. A tún le sọ pé ó jẹ́ òṣùwọ̀n láti fi wọn ijó agbè tó pegedé.

Olóhùn-agbè tí a dárúkọ nínú gbólóhùn méjì (èlé àti ègbè) tó parí orin òkè yẹn náà jẹ́ ọ̀kọrin agbè lásìkò tí Láǹgabà jẹ́ oníjó. Orin ni òun máa ń kọ jùlọ ṣùgbọ́n kò sí oníjó tirẹ̀ náà lẹ́yìn Láǹgabà fúnra rẹ̀. Àwọn kan tilẹ̀ ṣọ pé Láǹgabà náà ni Olóhùn-agbè ṣùgbọ́n Bàbá Tìámíyù Òjó fìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé olórin ni Olóhùn-agbè jẹ́, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé òun náà mọ̀ ọ́n jó dáradára. A wá le fi Láǹgabà wé òṣèré egúngún aláré, Lébe, tí ìtàn fi hàn pé òun ni ó mọ̀ ọ́n jó jùlọ, kí á fi Olóhùn-agbè wé Ẹ̀sà Ògbin tí a gbà pé ọ̀gá apẹ̀sà ni. Àmì ìṣeré (orin agbè kíkọ àti ijó) tó dára jùlọ ni Olóhùn-agbè náà ń pa nínú eré agbè.

Láti pe ara ẹni níjà nínú òkìtì títa, àwọn ajágbè máa ń kọ orin kí òṣèré tí ó ń tàkìtì tàbí pa idán le múra sí eré náà bí ó ti yẹ. Ẹ jẹ́ kí á wo àpẹẹrẹ ìsàlẹ̀ yìí:

Lílé: Ọmọ eléyìí yìí fò lókèlókè ò
Ègbè: Fò láálá

Lílé: Ọmọ eléyìí yìí fò lókèlókè ò
Ègbè: Fò láálá

'Fòlálá' ni orúkọ ijó òkìtì ti ajágbè tàbí olókìtì máa ń jó tí irúfẹ́ orin òkè yẹn fi máa ń wáyé nínú ìṣeré orin agbè. Nínú eré yìí, ajágbè yóó máa fò sókè lemọ́lemọ́, tí yóó sì máa ga ju gbogbo ènìyàn lọ. Ó le jẹ́ pé ewé igi ọdán ni ó fẹ́ rọ̀ mọ́ láti já, ó sì le fẹ́ fi ẹ̀yìn fo ohun kan tó ga fíofío. Bí ajágbè bá ti ń jó ijó olókìtì yìí ni àwọn ọ̀kọrin yóó máa fi orin pè é níjà kí ó túnbọ̀ fò dáradára sí, kí àfojúsùn rẹ̀ le jọ. Àpẹẹrẹ mìíràn ni orin tí àwọn ajágbè máa ń kọ láti pe oníjó/olókìtì níjà láti jó irúfẹ́ ijó idán kan tí àwọn ajágbè ń pè ní 'mẹ́taméta-ẹ̀là.' Láǹgabà ni a gbọ́ pé ó máa ń jó irúfẹ́ ijó yìí ni ìgbà ayé rẹ̀. Nígbà tí ajágbè kan bá ti jó dé ojú àmì ṣùgbọ́n tí àwọn ẹgbẹ́ rẹ̀ kò tí ì gbà á ní oníjó, wọ́n á wá sọ pé kí ó jó 'mẹ́taméta-ẹ̀là' yìí. Orin ni wọn yóó fi pe oníjó yìí níjà láti jó 'mẹ́taméta-ẹ̀là.' Orin náà ni a fi hàn ní ìsàlẹ̀ yìí:

Lílé: Mẹ́taméta ẹ̀là ò
Ègbè: Agogo ẹ̀là
Lílé: Mẹ́taméta ẹ̀là
Ègbè: Agogo ẹ̀là

Bí a bá wo irúfẹ́ orin yìí kan tí a ṣe àlàyé pé àwọn ajágbè ní ìlú Ìmia fi máa ń pe onílù agbè níjà láti lu agbè ní dídún mẹ́ta, orin náà fẹ́rẹ̀ bá eléyìí mu. Kì í ṣe pé oníjó nìkan ni orin 'mẹ́taméta-ẹ̀là' yìí ń bá wí, ó bá onílù náà wí. Ohun tí ó sọ fún onílù ni láti lu agbè, kí ajágbè le já agbè náà nígbà mẹ́ta. Bí ajágbè bá mọ ijó yìí í jó, ìgbàgbọ́ àwọn òṣèré orin agbè ni pé, ó gbọ́dọ̀ le fi ẹsẹ̀ rẹ̀ tó fi ń kilẹ̀ náà dẹ ọ̀gangan àyè tí ó ti ń jó ijó náà gẹ́gẹ́ bí Láǹgabà ṣe máa ń ṣe.



**Àwòrán 4**: Ajágbè gbẹ́sẹ̀ òsì sókè láti jó ijó idán 'mẹ́taméta-ẹ̀là'

Bí ajágbè kan bá le gbìyànjù láti ṣe báyìí, ọ̀gá oníjó idán ni àwọn ajágbè máa ń ka olúwà rẹ̀ sí. 'Mẹ́taméta-ẹ̀là' nínú ìṣeré orin agbè jẹ́ àròkò pàtàkì tí ó ń fi hàn pé eré ipá, àgbára àti àmúlò òògùn idán láti ṣe ohun àgbàyanu ni orin agbè jẹ́. Ó tún jẹ́ àmì láti fi hàn bí agbára ajágbè náà ṣe tó.

**Ìpèníjà nípa níní ìgboyà**

Ní àsìkò tí àwọn jagunjagun Ọ̀yọ́ ń lo orin agbè gẹ́gẹ́ bí ète ogun jíjà àti ohun ìmúnilọ́kanle lójú ogun ni irúfẹ́ ìpèníjà yìí wọ̀pọ̀ jùlọ. Ní àsìkò ọ̀làjú òde-òní, kò sí ogun abẹ́lé jíjà mọ́ ṣùgbọ́n síbẹ̀, àwọn ajágbè máa ń tọ́ka sí ọ̀rọ̀ ogun torí pé ó ní í ṣe pẹ̀lú ìpilẹ̀ṣẹ̀ orin agbè. Yàtọ̀ sí pé wọ́n máa ń lo orin agbè láti fi múra ẹni lọ́kàn le lójú ogun, àwọn ajágbè máa ń fi orin yìí múra wọn lọ́kàn le lásìkò tí a wà yìí, wọ́n sì fi máa ń gbara wọn níyànjú nígbà tí ìṣeré náà bá fẹ́ sú wọn. Ẹ jẹ́ kí á wo àpẹẹrẹ bí àwọn ọ̀kọrin agbè, tí a tún pè ní ajágbè ṣe máa ń fi orin agbè mú ara wọn lọ́kàn le àti láti ní ìgboyà nínú eré agbè gẹ́gẹ́ bí ó ti ṣe jẹyọ ní ìsàlẹ̀ yìí:

Lílé: Ṣẹ́ ó le è dúró o òeà?
Ègbè: Ẹ ò le dúró o òeà
Lílé: Ṣẹ ó le è dúró
Bẹ gbóhùn agbè ò?
Ègbè: Ẹ ò le dúró
Bẹ gbóhùn agbè ò

Ọ̀nà méjì ni a le gba túmọ̀ ẹni tí orin òkè yẹn ń báwí sí. Àkọ́kọ́ ni pé ó ń bá àwọn òsùnsùn-afọ̀ afòyemọ̀ wí. Èkejì ni pé ó ń bá àwọn òṣèré orin agbè mìíràn (bí àwọn oníjó/olókìtì) tó yàtọ̀ sí àwọn olórin wí. Nínú ìlà àkọ̀kọ́ orin òkè yẹn, alérin pe àwọn òsùnsùn-afọ̀ tí a kò rí níjà pé ǹjẹ́ wọn le dúró bí wọ́n bá gbọ́ ohùn agbè. Àwọn elégbè sì dá alérin náà lóhùn pé àwọn òsùnsùn-afọ̀ náà kò le dúró bí wọ́n bá gbọ́ ohùn agbè. Àwọn wo wá ni òsùnsùn-afọ̀ afòyemọ̀ wọ̀nyí? Gẹ́gẹ́ bí a ṣe sọ ní ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀, àwọn òsùnsùn-afọ̀ afòyemọ̀ yìí ni àwọn ọ̀tá, tí a fẹ́ láti fi kíkùrìrì agbè dẹ́rù bá, ìdí sì nìyí tí àwọn ọ̀kọrin náà fi là á mọ́lẹ̀ pé, àwọn ọ̀tá náà kò le dúró bí wọ́n bá gbọ́ ohùn agbè. Àmì ẹ̀rù/ìjáyà ni ohùn agbè dúró fún nínú irúfẹ́ ìlò yìí. Ní ọ̀nà kejì, ohùn agbè tí a sọ pé àwọn kan ò le dúró bí wọ́n bá gbọ́ tún le jẹ́ ohun ìdẹ́rùbá fún àwọn oníjó torí pé oníjó agbè ló ń ṣe iṣẹ́ tó le jùlọ nínú eré agbè. Àwọn ni ó máa jó sí ohùn orin àti sí ohùn ìlù tí a sọ pé ṣé wọn ó le dúró bí wọ́n bá gbọ́ ohùn rẹ̀. Láti le fi ara wọn hàn gẹ́gẹ́ bí ẹni tí kì í ṣọ̀lẹ, àwọn ajágbè gbọ́dọ̀ mọ̀ pé ìgbaniníyànjú ni orin òkè yẹn jẹ́, èyí yóò sì le jẹ́ kí wọ́n mú ọkàn wọn le dan-indan-in fún ìṣeré náà.

Nígbà mìíràn, àwọn ajágbè a tilẹ̀ máa là á mọ́lẹ̀ pé gbìì kan kò ju ikú lọ àti pé kò yẹ kí ohun kan wà tí ó yẹ kí ó dẹ́rù ba ọdẹ gẹ́gẹ́ bí Yorùbá ṣe máa ń sọ pé, “Gbàmígbàmí kò yẹ àgbà, ẹranko ń lé mi bọ̀ wá kò yẹ ọdẹ.” Láti mú ara wọn ní ọkàn le, orin ìsàlẹ̀ yìí jẹ́ àpẹẹrẹ orin agbè tí àwọn òṣèré orin agbè máa ń kọ.

Lílé: Fẹrẹkúfẹ
Ègbè: Ẹ̀rù la jọ ń dá bara wa
Lílé: Fẹrẹkúfẹ
Ègbè: Ẹ̀rù la jọ ń dá bara wa...

Bí a bá wo ìpède “Fẹrẹkúfẹ” tí ó jẹyọ nínú orin òkè yẹn, Ó fẹ́rẹ̀ jẹ́ pé ọ̀rọ̀ náà kò ní ìtumọ̀ àdámi/ajẹ́mọ́sẹ̀mańtíìkì kankan. Torí náà, a kò le rí ìtumọ̀ fún un nígbà tí a kò bá lò ó nínú ìhun ọ̀rọ̀. Ohun tó jẹ́ kí èyí rí bẹ́ẹ̀ ni pé ọ̀rọ̀ náà kò tọ́ka sí ohun kankan nínú ayé. Ìdí nìyí tí a kò fi le rí ìtumọ̀ rẹ̀ nínú ìwé atúmọ̀ èdè. Kóòdù aláìnítumọ̀ (*nonsensical code*) ni Riffaterre (1978) pe irúfẹ́ ọ̀rọ̀ yìí nínú ewì. Bí a bá tún wo àlàyé Ọlátẹ́jú (1998), ídíófóònù ni ọ̀rọ̀ náà, nípa ìlò wọn pẹ̀lú àwọn ọ̀rọ̀ mìíràn nínú gbólóhùn ni a ṣe le sọ ìtumọ̀ wọn. Bí a bá tọpa “Fẹrẹkúfẹ” sí inú ìhun ìpèlẹ̀ rẹ̀, “fẹ̀rẹ̀” ni ọ̀rọ̀ àpọ́nlé ìpìlẹ̀ tí a ti ṣẹ̀dá ọ̀rọ̀ náà. Ídíófóònù aṣàpọ́nlé ni “fẹ̀rẹ̀” yìí jẹ́. Èyí máa ń jẹyọ pẹ̀lú ọ̀rọ̀ ìṣe tó fi òye eré sísá, ìfò fífò, inú dídùn tàbí ayọ̀ yíyọ̀ hàn. Ẹ jẹ́ kí á wo àwọm àpẹẹrẹ ìsàlẹ̀ yìí níbi tí “fẹ̀rẹ̀” ti jẹyọ:

i. Ó fò **fẹ̀rẹ̀**
ii. Ó yọ̀ **fẹ̀rẹ̀**
iii. Ó ń dunú **fẹ̀rẹ̀**

Nígbà tí aṣafọ̀ so “fẹ̀rẹ̀” méjì pọ̀ nípa lílò wúrẹ́n àyísódì “kí” ni a máa ń ní àyọrísí “fẹrẹkúfẹ” gẹ́gẹ́ bí a ṣe fi hàn ní ìsàlẹ̀ yìí:

Fẹ̀rẹ̀ + kí + fẹ̀rẹ̀ ⟶ Fẹrẹkífẹ ⟶ Fẹrẹkúfẹ

Ohun tí a le túmọ̀ ọ̀rọ̀ yìí sí pọ̀ díẹ̀, a le túmọ̀ “Fẹrẹkúfẹ” sí erékéré, ara àyájù, ìdẹ́rùbani, àìdúró àti àìbẹ̀rẹ̀, ìdúnkookòmọ́ni àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Bí a bá wá wo bí a ṣe lo ọ̀rọ̀ náà nínú orin agbè òkè yẹn, ìtumọ̀ tí a le fún un ni ‘ìdẹ́rùbà gbogbo ìgbà’, ‘àìdúró àti àìrósẹ̀’ àti ‘ìfura àfujù’ tí ó máa ń dé bá àwọn jagujagun lójú ogun. Orin òkè tún fi hàn síwájú sí i pé orin ogun pọ́nńbélé ni orin agbè. Ṣé Yorùbá bọ̀, wọ́n ní, “Kò sí ohun tí ó máa pa àgbà tí a kò ní í bá poolo orí rẹ̀ níbẹ̀.” Báyìí ni ọ̀rọ̀ rí fún àwọn ajágbè tí wọ́n lo orin yìí gẹ́gẹ́ bí ète ogun jíjà (wo Kíarìbẹ̀ẹ́, 2021 fún àlàyé kíkún) látijọ́. A le pe “fẹrẹkúfẹ” tí a fi bẹ̀rẹ̀ gbólóhùn orin yìí ní àmì ìdúrófún ẹ̀rù/ìjayà, èyí tí a tún sọ nínú ìlà kejì àti ẹ̀kẹrin orin yìí. Gbólóhùn kejì náà sì ni gbólóhùn ìmúnilọ́kanle tí ó jẹ́ iṣẹ́ pàtàkì tí orin yìí fẹ́ jẹ́.

**Ìpera-ẹni-níjà nípa àmúlò òògùn ìkà fún ogun jíjà**

Nígbà tí àwọn ajágbè, tí ó jẹ́ jagunjagun bá wà lójú ogun látijọ́, wọn a máa fi orin agbè rán ara wọn létí ohun tí ó yẹ láti ṣe. Èyí kò yọ ìlò òògùn ìkà sílẹ̀ ní ààyè tó bá ti jẹ́ dandan. Wọn a máa fi kìlọ̀ bí wọ́n ṣe ní òògùn búburú fún ogun jíjà lọ́wọ́ tó, wọn a sì máa fi èyí dẹ́rù ba ọ̀tá wọn. Ẹ jẹ́ kí á wo àpẹẹrẹ orin ìsàlẹ̀ yìí:

Lílé: Igbó ọ̀dájú la dé
Ègbè: Ọ̀dàn ọ̀dájú la dé
Lílé: Igbó ọ̀dájú la dé
Ègbè: Ọ̀dàn ọ̀dájú la dé
Lílé: Ońdè kan ń bẹ lọ́rùn mi...
Ègbè: Ońdè kan ń bẹ lọ́rùn mi kàǹkà
Lílé: Ońdè kan ń bẹ lọ́rùn mi...
Ègbè: Ońdè kan ń bẹ lọ́rùn mi wòòkò

Nínú orin òkè yẹn, àwọn ajágbè jẹ́ kí á mọ̀ pé àwọn ti dé igbó àti ọ̀dàn ọ̀dájú. Èyí jẹyọ nínú gbólóhùn èlé orin àti ègbè rẹ̀ tí ó wà ní ìlà kìn-ín-ní sí ẹ̀kẹrin. Igbó jẹ́ ibi tí àwọn igi ńláńlá wà, tí àwọn ẹranko buburú bíi ejò olóró sì máa ń gbé. Yàtọ̀ sí èyí, àwọn ọ̀rọ̀ oríṣiríṣi náà máa ń gbé inú àwọn igi ńláńlá bí ìrókò, arere, apá, oṣè, idí, wáwọ̀n, àràbà àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ tí ó wọ́pọ̀ nínú igbó dídí.

Ọ̀dàn ní tirẹ̀ jẹ́ ibi tí àwọn igi ńláńlá kò wọ́pọ̀ sí ṣùgbọ́n tí àwọn koríko kún ibẹ̀, èyí ló sì mú kí àwọn ẹranko tó máa ń jẹ ewé bí agùnfọn, ìgalà àti ẹfọ̀n wọ́pọ̀ níbẹ̀. Bí a bá wo owè Yorùbá tí ó sọ pé, “Kí á tó rí erin ó digbó, kí á tó rí ẹfọ̀n, ó dọ̀dàn,” irúfẹ́ ẹranko tí a le rí ní igbó àti ọ̀dàn ni òwe yìí tọ́ka sí. Ẹfọ̀n tí a sọ pé inú ọ̀dàn ló ń gbé yìí náà jẹ́ ẹranko abìjà. Àwọn ẹranko apẹranjẹ bíi kìnìhún, ẹkùn, àmọ̀tẹ́kùn, ajá igbó, ọ̀fàfà, akátá, ẹyẹ idì, ẹyá àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ kì í jìnnà sí ọ̀dàn torí pé ibẹ̀ ni àwọn ẹranko tí wọ́n máa ń pa jẹ ń gbé. Torí náà, àti igbó àti ọ̀dàn ni ó jẹ́ ibi tó léwu. Bí àwọn ọ̀kọrin yìí tún ṣe wá là á mọ̀lẹ̀ wí pé igbó àti ọ̀dàn ọ̀dájú ni àwọn dé yìí fi hàn pé ibi tó le, tó mú ewu lọ́wọ́ ni wọ́n wà. Yorùbá a máa tọ́ka sí ààyè tó le gẹ́gẹ́ bí “ibi tí ojú ọlọ́mọ kò tó” àti “igbó ọ̀dájú.” Igbó ọ̀dájú ni ojú ogun, ọ̀dàn ọ̀dájú sì ni pẹ̀lú. Láti le ṣe bó ṣe yẹ ní ìbámu pẹ̀lú àyè tí wọ́n wà náà ni àwọn ọ̀kọrin yìí fi jẹ́ kí á mọ̀ pé òńdè kan ń bẹ lọ́rùn àwọn, èyí tó rí kàǹkà/wòòkò. Kàǹkà nínú ìlò

yìí fi bí oǹdè náà ṣe tóbi, tí ó sì lóró tó hàn. Bákan náà ni ìtumọ̀ tí wòòkò náà ní nínú ègbè orin náà. Àmì bí agbára ìlò òògùn àwọn jagunjagun ajágbè yìí ṣe tó ni "oǹdè kàǹkà" àti "oǹdè wòòkò" dúró fún. Orin yìí lápapọ̀ sì jẹ́ ohun ìpèníjà fún àmúlò òògùn ìkà ní ojú ogun.

**Àgbálọgbábọ̀**

A ti ṣe àlàyé ní kíkún bí orin agbè ṣe jẹ́ orin ogun nínú ìwádìí yìí, a sì fi hàn pé láàárín àwọn jagunjagun Ọ̀yọ́ Ilé lásìkò Babáyẹmí Ìtíolú, tí a mọ̀ sí Aláàfin Ṣàngó ni orin yìí bẹ̀rẹ̀. A ṣe àlàyé pé àwọn jagunjagun tí ó tẹra mọ́ orin agbè ni Gbọ́nńkáà àti Àfọ́njá, tí ó jẹ́ Ààrẹ Ọ̀nà Kakaǹfò ilẹ̀ Yorùbá lásìkò Aláàfin Aólẹ̀. A ṣe àlàyé pé Àfọ̀njá ni ó mú orin náà dé Ìlọrin. A tún ṣe àlàyé kíkún pé orin agbè náà ni àwọn kan ń pè ní ṣàkàrá. A sì sọ pé ìyàtọ̀ tó wà láàárín agbè/ṣàkàrá àti ṣẹ̀kẹ̀rẹ̀ ni pé èso tàbí ìlẹ̀kẹ̀ tó le koko ju èyí tí a fi ń sín ṣẹ̀kẹ̀rẹ̀ lọ ni a fi ń sín agbè. A fi kún àlàyé wa pé bí agbè tí a sín ṣe wà náà ni èyí tí a kò sín wà.

A kò ṣài ṣe àlàyé kíkún lórí bí àwọn ajágbè ṣe máa ń pe ara wọn níjà nínú eré agbè. Àwọn àlàyé wa nípa èyí dá lórí ìpera-ẹni-níjà nínú agbè lílù, orin kíkọ, ìṣeré ojúlówó, ijó jíjó/òkìtì títa/idán pípa fún ìdárayá, níní ìgboyà àti ìpera-ẹni-níjà nípa àmúlò òògùn ìkà fún ogun jíjà. Ó yẹ kí á tún ṣàlàyé ráńpẹ́ pé ní àsìkò yìí, kò sí ogun jíjà tí ó pilẹ̀ eré agbè ṣíṣe mọ́, torí náà, gbogbo ìpéníjà tí ó ń wáyé nínú eré agbè lásìkò òde òní wà fún ìdárayá àti ìdánimọ̀ pọ́nńbélé. Nípa ìdánimọ̀ yìí ni bí àwọn ajágbè ṣe máa ń tọ́ka ojúlówó ọmọ ọkọ ilé wọn pẹ̀lú ìṣeré orin agbè tó jíire tí òṣèré kan ṣe.

**Ìwé Ìtọ́kasí**


Àlàbá I. O. (1985). *A socio-stylistic analysis of Orin Agbè*: A multimodal genre of Yorùbá oral poetry, àpilẹ̀kọ fún òyè Ph.D, Department of African Languages and Literatures, Faculty of Arts, University of Lagos.

Cobley, P. and Jansz, L. (1999). *Introducing semiotics*. United Kingdom: Icon Books.

Eco, U. (1976). *A theory of semiotics.* U.S.A: Indiana University Press.

Kíaríbẹ̀ẹ́, L. A. (2021). Ewì gẹ́gẹ́ bí Ètè Ogun Jíjà Láwùjọ Yorùbá, *Yorùbá Studies Review*, Falola Toyin, Akintunde Akinyemi and Adejumo Arinpe (Eds), *vol. 6. No. 1*. Spring 2021, pp. 73-90. Texas, Florida in U.S.A. and Ìbàdàn, Nigeria.

____________ (2022a). Social Status of *Agbè* and *Kete:* A Historical and Functional Yorùbá Oral Literary Perspectives, *Notion: Journal of Linguistics, Literature and Culture*, *vol. 4(2*), 76-84.

___________ (2022b). Àgbéyẹ̀wò Pípe Àkíyèsí Àwùjọ sí Ìlera wọn gẹ́gẹ́ bí ó ṣe máa ń Jẹyọ nínú Orin Ìbejì àti Orin Ẹgbẹ, *Yorùbá: Journal of Yorùbá Studies Association of Nigeria*, Olumuyiwa, T. (ed.), *vol. 10. No. 2*, 41-54.

__________ (2023). *A comparative performance semiotics of Orin Kete and Orin Agbè among the Ìbàràpá and Òkè-Ògùn people of Yorùbá, Nigeria, àpilẹ̀kọ fún òyè* Ph.D, Department of Linguistics and African Languages, Univerisity of Ibadan.

Ògúndèjì, P.A. (1988). *Semiotic study of Duro Ladipọ's mythico-historical plays, àpilẹ̀kọ fún òyè Ph*.D, Department of Linguistics and African Languages, University of Ibadan, Nigeria.

____________ (1991). *Introduction to Yorùbá oral literature*. Ibadan: University of Ibadan Centre for External Studies.

Ọlátẹ́jú, M. O. A. (1998). *A syntactic approach to literary discourse analysis:* The Yorùbá example, àpilẹ̀kọ fún òyè Ph.D, Department of Linguistics and African Languages, University of Ibadan, Ibadan.

Ọlátúnjí, O.O. (1984). *Features of Yorùbá oral poetry*. Ibadan: University Press PLC.

Olúkòjú, E. O. (1978). *The place of chant in Yorùbá traditional oral literature, àpilẹ̀kọ fún òyè* Ph.D, Department of Linguistics and African Languages, University of Ibadan, Ibadan.

____________ (1985). Some features of Yorùbá songs, *West African Languages*, Williamson, K. (ed), *No. 38*, 251-263.

Ọ̀pádọ̀tun, Ọ. (2002). *Okòó ewì alohùn*. Ọ̀yọ́: Odumatt Press & Publishers.

Ọ̀pádọ̀tun, Ọ., Gbénró, D. and Ọmọ́làsóyè, A. (2005). *Ewì alohùn Yorùbá pẹ̀lú fọ́nrán oníf́ídíò: Apá kìn-ín-ní*. Ọ̀yọ́: ODUMATT Press and Publishers.

Raji, S. M., Adéọlá, J. O., Òjó, I. F., Táíwò, S. A. and Àjùwọ̀n. (2009). *Ọ̀kan-ò-jọ̀kan-ewì alohùn Yorùbá*. Ìbàdàn: Amazing Grace Computer.

Sebeok, T. A. (2001). *An introduction to semiotic: Second edition*. Toronto: University of Toronto.

Recebido em: 23/02/2025
Aceito em: 24/06/2025

**Para citar este texto (ABNT):** KÍARÍBẸ̀Ẹ́**,** Luqman Abísọlá. Ìpera-ẹni-níjà nínú Ìṣeré Orin Agbè. *Njinga & Sepé: Revista Internacional de Culturas, Línguas Africanas e Brasileiras*. São Francisco do Conde (BA), vol.5, nº Especial I, p. 172-187, jan./jun.2025.

**Para citar este texto (APA):** Kíaríbẹ̀ẹ́**.** Luqman Abísọlá (jan./jun.2025). Ìpera-ẹni-níjà nínú Ìṣeré Orin Agbè. *Njinga & Sepé: Revista Internacional de Culturas, Línguas Africanas e Brasileiras.* São Francisco do Conde (BA), 5 (Especial I): 172-187.